# ÀKASỌ JAKỌBU

## Gẹnẹsisi 27:41-46; 28:1-22

## ẸKỌ 23 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ọlọrun aiyeraiye ni ibugbé rẹ, ati nisalẹ li apa aiyeraiye wà" (Deuteronomi 33:27).**

**I Ètò Rebeka fun Sisá Jakọbu**

1. Esau pinnu lati pa arakunrin rẹ̀ nitori ire ti a sú fun un, Gẹnẹsisi 27:41, 36
2. Eto iya rẹ lati mu ki Jakọbu sá lọ si ile arakunrin rẹ̀ ni Harani, Gẹnẹsisi 27:42-45
3. Ọgbọ́n ẹtan ti Rebeka fi rán Jakọbu jade lọ si Harani lati wá obinrin kan fun aya, Gẹnẹsisi 27:46

**II Isaaki Fọwọ si Lilọ Jakọbu**

4. Ikilọ rẹ̀ fun Jakọbu lati má fẹ aya laaarin awọn ara Kenaani bi ko ṣe ninu awọn ọmọbinrin Labani, Gẹnẹsisi 28:1, 2; 24:2-4
5. Adura Isaaki pe ki ibukun Abrahamu lè wá sori Jakọbu; a si rán Jakọbu lọ si Harani, Gẹnẹsisi 28:3-5
6. Esau fẹ́ tẹ́ awọn obi rẹ̀ lọrun nipa yiyan aya ninu awọn ọmọbinrin Iṣmaẹli, Gẹnẹsisi 28:6-9; 26:34, 35

**III Àlá Jakọbu ni Ọna Rẹ̀ si Harani**

7. O dubulẹ oun nikan ninu igbẹ ni alẹ́, o fi okuta ṣe irọri, Gẹnẹsisi 28:10, 11
8. Alá rẹ̀ nipa akàsọ̀ ti o kan Ọrun, lori eyi ti awọn angẹli n goke ti wọn si n sọkalẹ, Gẹnẹsisi 28:12; Heberu 1:14; Johannu 1:51
9. Isọdọtun majẹmu Ọlọrun pẹlu Abrahamu, Gẹnẹsisi 28:13-15; 12:2, 3; 26:1-4

**IV Ibẹru Jakọbu ati Ẹ̀jẹ́ rẹ̀ fun Ọlọrun**

10. Ibẹru pe Ọlọrun sun mọ tosi rẹ̀ nigba ti o ji, Gẹnẹsisi 28:16, 17; 27:12
11. Lati sun mọ Ọlọrun si i, o gbé okuta ró, o si ta ororo si i lori, Gẹnẹsisi 28:18; Ẹksodu 29:36
12. Ibi mimọ́ nì, ti Abrahamu gbadura, ti a n pe ni **Bẹtẹli**, "ile Ọlọrun," Gẹnẹsisi 28:19; 13:3, 4; Isaiah 56:7
13. Ẹ̀jẹ́ Jakọbu lati san idamẹwaa gẹgẹ bi Abrahamu ti ṣe, abayọrisi majẹmu Ọlọrun, Gẹnẹsisi 28:20-22; 14:20; 18:19

## ALAYE

Igbesi-ayé Jakọbu ati Esau ni a ti ṣeto rẹ̀ lati ọdọ Ọlọrun wá gẹgẹ bi asọtẹlẹ Malaki: "Arakunrin Jakọbu ki Esau iṣe? li OLUWA wi: bẹli emi sa fẹ Jakọbu, Mo si korira Esau." Ọlọrun ti O mọ̀ ọkàn awọn ọmọ eniyan ti ri iyatọ laaarin ọkàn awọn ọmọde-kunrin wọnyi, ani ki a tilẹ to bí wọn. Ipò ti Jakọbu aburo yoo si di mú laaarin awọn ayanfẹ Ọlọrun ni a fi hàn nipa orukọ ti a fi fun un lakoko ti a bi i: itumọ **Jakọbu** ni "lati jin ni lẹsẹ" tabi "lati fi eru gba ipo ẹlomiran."

Ṣugbọn ki i ṣe ẹtọ Jakọbu tabi ti iya rẹ̀ lati gba ọ̀na arekerekè ati ẹ̀tàn lati mu eto Ọlọrun ṣẹ ki Jakọbu ba le gba ileri ati ibukun rẹ̀ wọnni. Ọlọrun kò fi igba kan gbẹkẹle ọgbọ́n ọmọ eniyan lati mu eto Rẹ̀ ṣẹ, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti iwa aiṣootọ́ wọn lati mu ifẹ inu Rẹ̀ ṣẹ. Ọlọrun kò gba ẹ̀ṣẹ ni àyè ri lọnakọna. O mu ètò ti Rẹ̀ ṣẹ o si tun majẹmu Rẹ̀ pẹlu Jakọbu di ọtun, ti O ti ba Abrahamu dá, O sọ aburo di ajogun ileri majẹmu Rẹ̀ -- ki i ṣe nitori iwa arekerekè Jakọbu ati iya rẹ̀, ṣugbọn lai ka buburu iṣe wọn si.

Bi a ba fi oju ti ara gẹgẹ bi eniyan wo o, Esau jare lati ni iru èro ti o ni si aburo rẹ̀. O rọrun fun ọkàn ẹlẹṣẹ lati fẹ gbẹsan ati lati bori alatako rẹ̀. Eyi lo mu ki Esau gbero lati pa Jakọbu lẹyin ikú baba wọn nitori kò mọ Oluwa Ẹni ti O sọ fun awọn ti wọn n tẹle E pe, "Temi ni ẹsan, emi ó gbẹsan." Apẹẹrẹ ti Kaini ati aigbẹsan pipa ti o pa Abẹli ti to lati fi hàn Esau pe oju Oluwa ri gbogbo ẹ̀ṣẹ awọn ọmọ eniyan O si n kiyesi wọn, ati pe, ni akoko ti Rẹ̀, Oun yoo mu olukuluku ẹlẹṣẹ wá si idajọ.

Rebeka tun lo ẹtàn o si gba aṣẹ lọdọ Isaaki fun Jakọbu lati fi ilu silẹ, o si mu un ki o sure fun un. Pẹlu bi gbogbo nnkan ti ri, ibẹru ikú ti n rọ̀dẹdẹ lori rẹ̀, rukerudo ti wà laaarin ẹbi, Jakọbu mu ọ̀na ajo rẹ̀ pọ̀n.

Nigba ti o di alẹ ọjọ kin-in-ni o duro lati sinmi ni gbangba ita kan. Kò si ibi irọrun fun un nibẹ; o si jẹ ohun ti o dara ju lọ fun un pe o wà oun nikan ṣoṣo pẹlu Ọlọrun, nitori nihin ohun kan ṣẹlẹ eyi ti o mu iyipada wá si gbogbo igbesi-ayé rẹ̀.

Ninu oorun rẹ̀ o lá àlá daradara kan. O ri àkasọ kan lati ilẹ de Ọrun ati awọn angẹli lori rẹ̀, ti wọn n goke ti wọn n sọkalẹ. Oluwa duro loke rẹ̀ O si ba Jakọbu sọrọ, O tun n ṣe atunwi ti majẹmu ti a bá Abrahamu dá tẹlẹ ri, pe lati inu iru ọmọ rẹ̀ ni a o ti bukun fun gbogbo idile ayé. Ọlọrun tun fi eyi kun un pe Oun yoo wà pẹlu Jakọbu lọna ajo rẹ̀, pe ọwọ Oun yoo maa wà lara rẹ̀ nigba gbogbo, ati pẹlu pe, Oun yoo tun mu un pada wá si ilẹ baba rẹ̀, Isaaki.

A rán ileri yii lati lé ibẹru kuro lọkan isansa yii ẹni ti o bẹ̀ru ibinu arakunrin rẹ̀ ati ijà ti yoo maa wà laaarin wọn nigba gbogbo. Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe ọrọ Ọlọrun wọnyii to lati lé ẹru yii lọ, sibẹ Jakọbu ni ẹ̀ru miiran lookan àyà rẹ̀. Eyi ni ibẹru Ọlọrun -- Ọlọrun Ẹni ti oun kò fi sinu ero rẹ̀ tẹlẹ ri, ati niwaju Ẹni ti oun kò si le sá kuro tabi fara pamọ. A le ja aja-bọ́ kuro ninu ijiya aṣiṣe wa lọdọ awọn ẹlẹgbẹ wa, ṣugbọn ohun kan daju: a kò le sá kuro niwaju Ọlọrun ti O ri ohun gbogbo.

Lati bọ́ kuro lọwọ idalẹbi ọkàn yii ohun kan ṣoṣo ni o le ṣe: o ni lati jẹwọ irekọja rẹ̀ gbogbo ki o si bá Ọlọrun dá majẹmu. O ṣe eyi nipa gbigbe okuta kan kalẹ fun pẹpẹ ati nipa adura ti o gbà nibẹ.

O hàn gbangba pe Ọlọrun gbọ́ adura yii, nitori Oluwa pada di Ọlọrun Jakọbu. Jakọbu si pe ibẹ ni **Bẹtẹli**, eyi ti i ṣe **Ile Ọlọrun**. A dá Jakọbu nide: a si ri i pe gbogbo iwa rẹ̀ yí pada lati igba yii lọ. Iyanu ni iṣẹ Ọlọrun wa! Ni iṣẹju kan ẹ̀bi on idalẹbi ẹ̀ṣẹ a si fò lọ eyi a si mu ibẹ̀ru idajọ Ọlọrun kuro, ẹlẹṣẹ a si gba alaafia ti idariji ẹ̀ṣẹ nigba ti o ba bẹbẹ fun aanu ati ifiji ẹ̀ṣẹ lọdọ Ọlọrun.

Esau jẹ́ apẹẹrẹ awọn eniyan ti o kun fun ifẹ ayé, ti wọn n lepa ohun igba isisiyii, ti wọn kò si le wo ọjọ iwaju lati ri oṣi ati ègbé wọn fun kikọ awọn ibukun ti ẹmi silẹ. Jakọbu rán wa leti awọn ti wọn kò ni itẹlọrun ninu ipo iṣọtẹ wọn si Ọlọrun, ṣugbọn ti wọn n ṣafẹri ohun ti o dara ju ti wọn si n ro ti èrè ati ọpọ ibukun ti o le jẹ ti wọn.

Akasọ ti Jakọbu ri pẹlu ogunlọgọ awọn angẹli lori rẹ̀ jẹ apẹẹrẹ ọ̀na naa nipa eyi ti a fi n mu eniyan wá sọdọ Ọlọrun. Ni atetekọṣe ẹṣẹ mu ibi nla kan wa – ipinya laaarin eniyan ati Ọlọrun -- Ọlọrun si ṣèto pe gbogbo ẹni ti o ba fẹ le pada ki o si ni idapọ pẹlu Rẹ̀. Lati ṣe eyi o yẹ ki Onilaja kan ki o wà. Kò si ẹni ti o le gba ipo yii bi ko ṣe Jesu Ọmọ Ọlọrun, bẹẹ ni a ti ṣe eto yii lati ipilẹṣẹ ayé wá pe Oun ni yoo wá ki O si fọ́ Satani lori, ti yoo si pese iranwọ nipa eyi ti eniyan yoo fi ni idapọ pẹlu Ọlọrun.

Jesu de ni akoko ti o tọ́, O si jiya fun araye, O si di “Àkasọ” naa gẹgẹ bi a ti le wi, nipa eyi ti a fi le goke tọ Ọlọrun lọ ati nipa eyi ti a o fi le mu èto Ọlọrun ṣẹ. Awọn angẹli nihin jasi ẹmi ti n jiṣẹ ti a n rán lọ lati maa jọsin fun awọn ajogun igbala (Heberu 1:14). Jesu tọka si iran naa ati imuṣẹ rẹ si I lara nigba ti O wi fun Nataniẹli pe, “Ẹnyin o ri ọrun ṣí silẹ, awọn angẹli Ọlọrun yio si ma gòke, nwọn o si ma sọkalẹ sori Ọmọ-enia” (Johannu 1:51). Nataniẹli nipa imoye ti ẹmi, mọ pe Jesu ni “àkasọ” naa tabi ẹbùn oore-ọfẹ fun araye ti o ti ṣubu, ati pe awọn angẹli jẹ awọn ẹni ti o ṣe iranwọ ninu eto nla yii ti Ọlọrun ṣe.

Onipsalmu sọtẹlẹ bayii pe: “Ãnu ati otitọ padera; ododo ati alafia ti fi ẹnu kò ara wọn li ẹnu. Otitọ yio rú jade lati ilẹ wá: ododo yio si bojuwò ilẹ lati ọrun wá” (Orin Dafidi 85:10, 11).

Awọn olorin ti gbiyanju lati sọ ti itan nlá nlà yii ati ipa ti o kó ninu iṣẹ igbala wa. Ọkan kọ bayi pe:

**“Ni ọna àjo mi, bi ’lẹ ba ṣu**
**Bi okuta si jẹ irọri mi;**
**Sibẹ, nin’ala mi,**
**N o sunmọ Ọlọrun**
**N o sunmọ Ọ.”**

**“Nibẹ jẹ ki n rọna**
**To lọ s’Ọrun,**
**Gbogb’ohun t’O fun mi**
**Nin’anu Rẹ**
**Angẹl lati pe mi,**
**Sunmọ Ọlọrun mi,**
**N o sunmọ Ọ.”**

Ẹlomiran tun fi oye kọ bayii pe:

**"N o kuku bá Jesu nikan rin,**

**Ki n si fi okuta ṣe 'rọri mi bi Jakọbu**

**Ki n ma wo oju Rẹ̀ ni wakati gbogbo**

**Ju pe ki n yà kuro nipa ọ̀na mi ki n si pada sẹyin."**

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti Jakọbu fi n lọ si Harani?
2. Iyipada wo ni iwà Esau mu wá si igbesi-ayé Jakọbu?
3. Ki ni Rebeka sọ fun Isaaki nipa ijade lọ Jakọbu?
4. Ki ni Isaaki ṣe fun Jakọbu ki o to kuro ni ile?
5. Nibo ni Jakọbu sùn ni oru ọjọ kin-in-ni, ki ni ṣe ti a n pe ibẹ ni orukọ ti o n jẹ?
6. Ki ni Ọlọrun bá Jakọbu sọ ninu àlá?
7. Ta ni Jakọbu bẹrẹ si bẹru rẹ̀ nigba ti ilẹ mọ?
8. Ki ni Jakọbu ṣe lẹyin ti o jí?
9. Ki ni Jakọbu jẹjẹ lati ṣe nigba ti o gbadura?
10. Iriri oore-ọfẹ wo ni Jakọbu ri gbà nihin?